P.O

**OWE**

A NJUWỌN ko se wi tẹjo ija ilara ko tan boro.

Agbalagba ti yio te iletutu yio da omi siwaju igba ki i to lọ bi orere aiye ki i to lọ bi ọpa ibọn.


# Irohin Yoruba

No. 764 — JANUARY 27—FEBRUARY 2, 1960 — Kobo Meji (2D.)


**LAKAYE ORỌ**

OJU Oluwa mbẹ lara awọn olododo, eti Rẹ si ṣi si igbe wọn.
Oju Oluwa kan si awọn ti nṣe buburu lati ke iranti wọn kuro lori ile.
Awọn olododo nke, Oluwa si gbọ, o si yọ wọn jade kuro ninu iṣẹ wọn gbogbo.

# IPADE IGBIMỌ AWỌN AGBA-OṢELU BẸRẸ



OLOYE ADEBAYỌ DOHERTY — IYA-AFIN WURA ẸSAN — OLOYE T. A. ỌDUTỌLA, ỌGBẸNI ỌJA

EKO—NI ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹdọgbọn oṣu yi ni Igbimọ Awọn Agba-Oṣelu Apapọ Ijọba Naijiria ṣe ipade, pataki, ohun ti nwọn ṣe aṣaro lelori ni Ominira Ijọba Apapọ Naijiria ti Igbimọ Apapọ Ijọba Naijiria ti fi ipinnu si ninu ipade wọn ti nwọn ṣe ni ọjọ Ọjọbọ ti iṣe ọjọ kẹrinla oṣu yi ki Igbimọ Apapọ. Ijọba Naijiria na to mu ipade wọn wa si ipari ni ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kejilelogun oṣu yi.

Nigbati Igbimọ Awọn Agba-Oṣelu Naijiria bẹrẹ aṣaro lori ipinnu na ni Oloye Adebayọ Doherty ṣe alaye wipe, imọran ti o dara, ti o si tọna ni lati gba Ominira Ijọba na ninu ọdun yi nitoripe awọn oṣelu Naijiria ti wa lẹnu ijakadi a ti gba Ominira Ijọba yi lati ọdun 1920 ni Ilu Oyinbo ninu ọdun ti on pari ẹkọ on ni Ile-iwe-Gigajulọ ni Ilu Oyinbo,o si ṣe alaye ọpọlọpọ wahala ti o ti wa lori a ti gba Ominira Ijọba na lati ẹhin wa titi di igbati Igbimọ Apapọ Ijọbá Naijiria fi opin si ti Ominira Ijọba na.

O si tun ṣe alaye siwaju pe, nigbati on wa ni ọmọ Ile-iwe Ẹkọ Giga "King's College" Eko, on ko ri ki ẹnikan ya ẹnikan sọtọ pe, Yoruba re e tabi Ibo re e. Ifẹ Mapo orilẹ-ede Naijiria jinlẹ lokan gbogbo enia nigbana. O ni vugbon lode ti oni yi, orişirişi iyatọ ni a si nri larin ẹya orilẹ-ede Naijiria ti ko le ṣe anfani kan fu ilu wa, afi bi a ba yi iwa na pada.

O si tun sọ siwaju pe, ohun ti o mu ki nwọn fi da Igbimọ Awọn Agba-oṣelu silẹ ni pe ki o ma ba si iyatọ larin awọn ẹya orilẹ-ede Naijiria, o si tun sọ pe, Igbimọ Apapọ Ijọba Naijiria nilati tun ṣe Eto Iṣelu titun lẹhingbigba Ominira Ijọba ki irẹpọ larin orilẹede Naijiria ba tubọ le fidimulẹ.

Lẹhin ti diẹ ninu awọn Aṣoju Igbimọ na sọrọ si i ati Alaiyeluwa Ọba Adele Keji, Ọba Eko, nwọn si pinnu pe, awọn gba ipinnu Igbimọ Apapọ Ijọba Naijiria lori ọran Ominira Ijọba Apapọ Naijiria.

## Ọran Alafin-ana ko kan Igbimọ Apapọ Ijọba

EKO.

NI ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kejilelogun oṣu yi nigbati Igbimọ Apapọ Ijọba Naijiria nṣe ipade ti Ọgbẹni R. O. A. Akinjide, aṣoju Ẹgbẹ Olomi(NPC) mu ẹnu kan ọran Alhaji Adeyẹmi, Alafin ana ti Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ti rọ oye nṣe ni Alaga Igbimọ na fi ye e lẹmẹta pe ona ti o lodi si eto Igbimọ ni o gba lati sọ nipa ọran na.

Ọgbẹni Akinjide ka ẹsun si Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun lorun, oni lẹmẹta ni Ijọba na jẹ Alafin na ni iya fun ẹṣẹ kanṣoṣo na, Alaga Igbamọ Apapọ Ijọba Naijiria si sọ ọ fun un lojiji pe ko ni ẹtọ lati tako Ijọba Ipinlẹ ninu Igbimọ Nla na ti nwọn nṣe.

Nigbati Ọgbẹni Akinjide tun dide lẹkeji, o sọ lori ọran kanna pe, "Mo ni ireti pe awọn Iriju Apapọ Ijọba yio dide si ọran na lọdọ awọn alaṣẹ lori rẹ ni Alaga Igbimọ na ba tun sọ fun un pe ki o ye e gba ona ti o lodi sọro na mọ. Nigbati o si tun dide lati tun sọ lori ọran kanna ni Alaga ba ni ki o joko.

Ọgbẹni Lana Aṣoju Ẹgbẹ Olomi (NPC) ninu Igbimọ na ni ki Apapọ Ijọba Naijiria lo ofin Ẹtọ pataki ti awọn Enia ni (Fundamental Human Rights) ti o wa ninu ofin Naijiria fi mu Alafin na wa si Ọyọ pada. Malam Usman Sarki, Minista Alamojuto Ọran Ilu si sọ pe Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ni ọran Alafin na wa ni ikawọ rẹ. O ni on yio ṣe iwadi nipa rẹ, bi o ba si ti yọri si nwọn yio ma a gbọ.

## Ẹdẹgbẹta enia ṣegbe sinu iho-ilẹ

LAIPẸ yi ni ilẹ ya bo ẹdẹgbẹta enia (500 people) ti nwọn nṣiṣẹ ninu iho-ilẹ nibiti nwọn gbe wa edu ni ilu Coolbrook, ni Iha Gusu Afirika (South Africa).

Awọn okuta nla meji ni o yalu koto na ti oke koto na fi wo lugbogbo awọn ti o wa ni isalẹ koto na mọlẹ, enia-dudu mẹfa pere ni o wa ninu awọn ti ilẹ ya bo na. Ọpọlọpọ awọn enia ni o ṣe wahala lati gbe ilẹ kan wọn, ṣugbọn aṣeti ni lati gbẹlẹ de ibiti nwọn wa.



Aworan oke yi ni ti igbati Oloye Akin Dẹkọ, Minista Alamojuto ohun Ọgbin ati Iṣura-ilẹ Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun nṣe alaye fun awọn enia ni Gbọngan Apejọ Itoro, Ijẹbu-Ode laipẹ yi nipa eto oko-titun ti Ijọba tẹdo fun awọn agbẹ Ẹlẹgbẹ-alajumọṣe (Co-operative Farm Settlemnt) lelẹ laipe yi.

## Ajigbaiye ko ọmọjade

AKWANTIA, GHANA.

NI ọjọ Ọjọbọ ti iṣe ọjọ kẹrinlelogun oṣu kejila ọdun ti o kọja yi ni Ọlọrun fi ọmọbirin kan ta Ọgbẹni Salami Ajibaiye, Aṣoju Iwe "Irohin Yoruba", ati iyawo rẹ, Sẹlia Ajia lọrẹ, nwọn si ko ọmọ na jade ni ọjọ kẹjọ ti nwọn bi i, nwọn sọ orukọ rẹ ni Kudiratulah Abikẹ Abiọdun. Awọn obi ọmọ na fi jijẹ ati mimu tẹ gbogbo awọn alabaṣẹyẹ ọjọ na lọrun.

..ẹ ti aye wa fun lati darukọ ninu awọn alabaṣẹyẹ ọjọ na ni awọn Ọgbẹni Jimoh Arẹmu, Lawani Arẹmu, Salawu Alao, Sanni Giwa, Suberu Jato, Bello Kola, Garuba Awẹda, Sadiku Ajani, awọn Iyaafin Bellau Arinpe, Ṣifawu Ayinkẹ, Asimau, Mariama Esu ati Alhaja Ṣifawu Awẹro.

## Ọlọṣa kan tun lọ s'ẹwọn ẹkẹjọ

YABA.

LAIPẸ yi ni Adajọ Kotu Kekere Yaba so Mallam Damandara, ẹniti ko ni iṣẹ kan lọwọ ti ko si tun ni ibugbe s'ẹwọn oṣu mejila fun ẹsun wipe o lọ f'ọle okunrin kan, Eugene Echimona ni 15, Ọnasanya Street, Surulere, o si ko o ni aṣọ-wiwọ o ni pọnun mẹsan ati ṣile mẹrin ni alẹ ọjọ kẹdogun oṣu keje ọdun ti o kọja yi.

Nigbati awọn ọlọpa nro ẹjọ nwọn ni ni Abẹokuta ni ọdaran yi ti bẹrẹsi ṣe iṣẹ olejija ni nkan bi ọdun kọkanla sẹhin, ṣugbọn ọdun kẹrin ti o ti w'ẹwọn kan gbẹhin niyi.


IRORA FẸRẸ JẸKI AWỌN APA KEJI NI IṢẸGUN!



1. Isẹju marun pere ni o ku ki nwọn fun fere ikẹhin ni Joe bẹrẹsi fi kokosẹ ṣẹṣẹ—o si ku bọlu-agbawọle kan ti nwọn yio fi ṣegun!

2. Joe dubulẹ si ilẹ, o nke'rora. Lojiji, ọrẹ rẹ kan sare to o lọ. O ni "fi eyi pa a," o si gbe idẹ Mentholatum [illegible] Joe.



3. Lẹsẹkẹsẹ ti o ti fi Mentholatum atura ati adẹra pa a, Joe bẹrẹsi gbadun. O ku iṣẹju kan ki nwọn fun fere ikẹhin.

4. Ah! Joe ti pada si aye awọn ti nwọn to si iwaju, o gba bọlu ti nwọn gba si i si apakan lojiji—o si gba a wọle! ọpẹlọpẹ Iwosan Mentholatum Joe ti gba ere-ije na la.

Bi o ba ni ẹsanra tabi irora tabi ẹfọri fi Mentholatum atura ati adẹra pa ibẹ. Lẹsẹkẹsẹ a ti mu riro na kuro nibẹ. Wa a si bẹrẹsi gbadun aiye. Mentholatum darajulọ fun jẹdijẹdi, pẹlu —a tete mu itura wa! Ri i daju pe, Men-tho-lay-tum gan an ni, ti o wa ninu awọn agolo ati idẹ bi irufẹ iwọnyi ni ki o ra. Maṣe ra awọn adamodi!



Awọn ti o nṣe e nikan ni

MENTHOLATUM CO. LTD.

(Est. 1889) Slough, England

MENTHOLATUM

IPARA TI O DARAJU


## Owe ilẹ Yoruba

1. Eepa npa ara rẹ, o ni on npa aja.
2. Bi Baase ko ba se, Baala ki i ri nkan fala.
3. Afopina pa ara rẹ, o ni on fi oyun-ọkọ jona.
4. Warapa si oju onisẹgun dena, ẹniti o mu ara wa a wo mẹhọ.
5. Gunnugun ṣoge titi, o pa lori, akalamagbo ṣoge titi, o yọ gẹgẹ lọrun, ẹhuru-ẹiyẹ ṣẹnu-gọngọ ko le fi gbẹ igi.
6. Aiko mọ orukọ ẹtu ni a fi npe ni obeje, ẹtu ni ẹtu njẹ.
7. Bi Esuro ba padida ti o nle aja, aja ni yio pa a jẹ.
8. Bi ekute-ilẹ ba di ojontarigi, ti o nki ologbo kuasan, ologinni yio si fẹsọ mu u.
9. Oju ki i pọn babalawo ki o bere ẹbọ ana.
10. Oju ki i pọn Mọjẹ, ki o ma ri ẹgbaa ayọna.
11. Ekolo mi gbagọ, inu mbi adiẹ ṣuṣu.
12. Bi oju ba npọn iṣin, apọnku kọ, apọnla ni.




Alapata ti o darajulọ nlọ si Banki ti o darajulọ.

BARCLAYS BANK D.C.O.

Iwọ, paapa, le bẹrẹsi fi owo rẹ pamọ sibẹ loni.


## IDIJE ORIRE

### FUN AWỌN ỌMỌ ILE-IWE

### PỌNUN KAN ṢILE KAN FUN ẸNITI O BA ṢE ORIRE

KỌ itan ti o dun ti o gun ti o si mu ẹkọ dani ni ede Yoruba ṣowọ si OLOTU IWE IROHIN YORUBA, 5/7, Apọngbọn Street, P. O. Box 163, Lagos, Nigeria.

## Eto ilana

(1) O ni lati kọ ẹkọ ti itan na mu dani pẹlu rẹ.

(2) O ni lati ge iwe yi ki o fi ṣowọ pẹlu itan na.

(3) Ẹniti tirẹ ba dara julọ, ao tẹ jade ninu Iwe Irohin Yoruba. Ẹniti o ba ri tirẹ ti o ba wa ni idalẹ ki o kọ iwe bere owo tirẹ, ki olukọ rẹ si fi ọwọ si iwe na, ṣugbọn awọn ti o ba wa ni Eko ati agbegbe rẹ ki o wa gba funra ara wọn pẹlu ijẹrisi olukọ wọn.

(4) Ẹniti a ko ba tẹ tirẹ jade ki o ri i ka, ko ni gba owo.

(5) Kọ orukọ rẹ sinu iwe eto yi bayi ki o si ge ṣowọ pẹlu itan rẹ bayi:—

Orukọ rẹ......................

Orukọ ile-iwe rẹ......................

Adugbo wo ni ile-iwe na wa......................

Kilasi ti o wa......................

(6) Ọmọ ile-iwe oniwe kini titi de iwe kẹfa ni o ni ẹtọ lati dije fun orire na.

# IROHIN KAKIRI ILẸ YORUBA

## Dọkita Aiyederu kan fi £120 tanran

IBADAN.

NI ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kẹsan oṣu yi ni Ọgbẹni M. A. Begho, Adajọ Kotu Kekere Ibadan ṣe idajọ pe ki ọkunrin ọdaran kan, Abọbade Ajani, ẹni ọdun mẹrindilogbọn fi ọgọfa pọnun (£120) tanran si Kotu tabi ki o lọ s'ẹwọn oṣu mejila nitoripe o jẹbi ẹjọ ti awọn ọlọpa ba a ṣe pe, nwọn ka egbogi ti o lewu mọ ọ lọwọ.

Ẹjọ ti awọn ọlọpa ba ọdaran na ro ni pe o pe ara rẹ ni adape orukọ "Dọkita Adeyẹmi Kọleosho" ati pe, awọn ri irin iṣe onişegun ti nwọn fi nyẹ alaisan wo ati abẹrẹ-dọkita mọkandilọgbọn pẹlu awọn oogun ti dọkita fi ngun abẹrẹ lọwọ rẹ, bẹẹ ko ni ẹtọ lati ni wọn lọwọ.

Ọdaran na dẹrinpa gbogbo awọn ti o wa ni kotu nigbati o nro ẹjọ ti o si ṣe alaye pe, on ṣebi on ti di dọkita niyẹn nigbati on ti kọ iṣẹ lọdọ ara Onitsha kan ni Ipinlẹ Ila-Orun on si ni igbagbọ pe, on ni aṣẹ lati lo awọn egbogi na ni on fi ra wọn ni oṣu kẹta s'ẹhin.

## *Igbeyawo Saka dun, o larinrin*

AGBEYE LẸBA OSHOGBO.

NI ọjọ Ọjọbọ ti iṣe ọjọ kẹtadilogun oṣu kejila ọdun ti o kọja yi ni Ọgbẹni Saka gbe Omidan Abibatu ni iyawo alarinrin ni agboile Balogun Agbeye, ẹsẹ gbogbo awọn ẹbi ọrẹ ati ojulumọ ọkọ iyawo ati iyawo na ti nwọn wa lati ilu okere bi Inlẹba, Ekọsin ati gbogbo agbegbe rẹ ni o peṣọṣọ ni ọjọ inawo igbeyawo na, ọkọ iyawo na si fi jijẹ ati mimu tẹ gbogbo awọn alabaṣẹyẹ na lọrun.

Diẹ ti aye wa fun lati darukọ ninu awọn alabaṣẹyẹ ọjọ na ni awọn Ọgbẹni Salawu Oyetoro, Tiamiyu Okunlọla, Oyebanji Sunday, Ọlapada Nathaniel, Ọlawore Lasisi, Awotunde Driver ati Jonathan Fajunmọ. Ki Oluwa fi ọmọ rere ṣikẹ iyawo ki o si fi ire kari gbogbo awọn alabaṣẹyẹ iyawo na o.



Aworan yi ni ti Ọba Alaiyeluwa Tẹwọgboye Keji, Osemowe Ondo, Ọba Alaiyeluwa Ọlagbeji Keji Ọlọwọ Ọwọ, ati Yeyesa i y a w o Ọlọwọ nibi ẹyẹ ifihan kini ti awọn Agbẹ ṣe ni Akurẹ ninu ajọdun wọn

## Ijọ Musulumi Makun ṣe ikore

SHAGAMU.

NI ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kẹwa oṣu kini ọdun yi ni awọn Ijọ Musulumi Makun ṣe ikore, ẹniti o ṣe alaga eto Ikore na ni Oloye Lawal Awoyẹmi, awọn isọngbe rẹ, Iyaafin Suwebatu Balogun, Ọgbẹni A. Ogunmẹkan ati E. Ọla. Ogunlesi, ẹniti o rọ waasi ikore na ni Alhaji Gbadiniga. Akọwe Ikore na ni Taiwo Pedro. Irohin ko to amojuba ni aṣeyẹ ajọdun ikore na.

Aṣeyi ṣamọdun o.

## Ijamba mọto pa enia mẹfa

IJẸBU-ODE.

NI irọlẹ ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kejila oṣu kini ni ọdun yi ni ijamba mọto kan ṣẹlẹ nibuṣọ merindilogoji larin ọna Ijẹbu-Ode si Eko, enia mẹfa ni o si ku lẹsẹkẹsẹ pẹlu dẹrẹba kan, Raji Adebayo ti o nwa ọkọ-ero nomba LD6677, nigbati ọkọ na fi ori gba mọto J1655 ti Karimu Oriọla nwa, ọpọlọpọ awọn ero inu mọto na ti ko ku lo fi ara pa.

Awọn ọlọpa ti nwọn lọ si ibi ijamba mọto na ṣe wahala pupọju ki nwọn to le yọ awọn oku ati awọn ti o tun farapa kuro l'abẹ mọto mejeji na ti nwọn f'ori gba'ari, kò si ti si ti o ku na fun awọn ọlọpa si Ile Lakulaku ni Shagamu. ohun ti o fa ijamba awọn ki nwọn to ko oku wọn lọ ẹnikan ti o le sọ orukọ awọn Awọn ọlọpa si wa lẹnu iwadi mọto na.

## Igbimọ Ijọba Ibilẹ Mushin ni ẹka ile-iṣẹ titun

MUSHIN.

LẸNULỌLỌYI ni Oloye Lamidi Suberu, Jagun Ṣomolu ṣi ẹka ile-iṣẹ titun ti Igbimọ Ijọba Ibilẹ Mushin fi ẹgbẹrin pọnun (£800) kọ pari si Ṣomolu. Nwọn yio si ma a se iṣẹ eto ilera ati owo-ori ati iṣẹ awọn ọlọpa Ijọba Ibilẹ nibẹ. Nipa bayi, awọn ara Ṣomolu yio bọ ninu wahala irin lati Ṣomolu si Mushin lati wa san owo- ori wọn.

## Awọn ọlọpa hu oku ọkunrin kan jade

IBADAN.

NI ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kọkandinlogun oṣu yi ni awọn ọlọpanu ri oku onişowo kan, Oyelakin Ajao, ẹni ọdun mọkandinlogoji ti o ti jade kuro ni ile rẹ lati ọjọ diẹ sẹhin hu jade lati inu aginju ni abule Jako, ibuṣọ mejidinlogun si Ibadan. O gba awọn ọlọpa na ni ọjọ mẹta ki wọn to ri oku rẹ na hu jade.

Nigbati Oyelakin lọ bẹ ọrẹ rẹ kan wo ni abule kan ti ko jinna si ile rẹ ni nwọn ko ri abọ rẹ mọ. Ọrẹ rẹ na ti o lọ bẹwo si sọ fun awọn ọlọpa pe, aṣọde-alẹ kan ti o pade awọn loju ọna nigbati on nsin in lọ ni alẹ ọjọ na ti ijamba na fi ṣẹlẹ sọ fun on pe, ki on maṣe ṣe iyọnu lati sin in jinna, o si ni on (aṣọdena) yio ṣe itọju rẹ.

Ọrẹ rẹ na tun sọ pe ologbe na mu owo ti o fẹ lati fi san owo-ori dani lọjọ na ti o wa si ọdọ on, eyi si ni o mu awọn ọlọpa lati ni ero pe, nitori owo na ni nwọn ti ṣe ṣa a pa. Apa ogbẹ kan ti nwọn fi ada ṣa wa ni ori rẹ, omiran si wa ni ẹhin ọrun rẹ.

Awọn ọlọpa ti mu awọn ọdaran mẹfa ti nwọn ni ifura si fun ọran na: awọn na ni Raufu Ajagbe, ẹni ogoji ọdun ati Arasi Adio, ẹni ọdun mejilelọgbọn fun ẹsun pe nwọn ṣa onişowo koko na pa; nwọn si mu awọn ọdaran mẹrin yoku, Daniel Adeniran, ẹni ọdun marundinlogoji; Joseph Adebisi, ẹni ọdun mejilelogun; James Olutayo, ẹni ọdun mẹrinlelogbọn ati Ladokun Akanni, ẹni ọdun marundilogoji fun ẹsun pe, nwọn ṣe iranwọ lati sin oku na. Nwọn yio si bẹrẹsi ṣe ẹjọ wọn ni ọjọ kẹrin oṣu tombọ yi.

## *Ọlọti Bọlugi fi £2 tanran*

IKẸJA.

NI ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kẹrindinlogun oṣu yi ni Adajọ Kotu Ijọba Ibilẹ Ikẹja ni ki ọdaran obirin arugbo kan Nusiratu Agbẹkẹ lọ san ogoji ṣile (£2); nitoriti o jẹbi ẹjọ ti awọn ọlọpa ba a ṣe pe, nwọn ka ọti bọlugi mọ o lọwọ ni Abule Ayọbọ, ni Agege ni ọjọ kẹtalelogun oṣu kejila ọdun ti o kọja yi. Ọdaran na si sọ fun Adajọ pe on jẹbi, ṣugbọn onişegun on ni o ni ki on fi ọti bọlugi na lu egbogi kan.



# ALAPARA IBADAN

ALAPARA—Olotu, ẹ ma ku ijọ mẹta.

OLOTU:—Aaloo! ọrẹ mi Ala-para Ibadan, iwọ ni a bi iwọ kọ? Tabi oju mi ntan mi jẹ ni?

ALAPARA:—Nda o, emi ni gan an ni ẹ ri yi, ẹiyẹ miran ki i jẹ adiẹ.

OLOTU:—Kini wa ti jẹ ki o to gbe-kese bẹ ẹ?

ALAPARA:—Asure- ninu - ẹkan ki iṣe oju asan ni temi, bi nkan ko ba nle, a jẹ wipe o nle nkan. Awọn agbalagba ni i si ma a pa loye wipe "A joko afi apo rọ, a naro tan owọ go to apo mọ" Ọrọ ti Sariyu yi na ni o ko aisan ba mi ti ẹ ko fi ri mi lati bi ọjọ mẹta.

OLOTU:—Kini iba fa a, Sariyu tun wa lodọ rẹ ni? Mo ṣe bi ohun ti o ti ṣelẹ ni arin nyin lati ọjọ pipẹ ni nsọ itan rẹ?

ALAPARA:—Bẹni, itan ọjọ pipẹ na ni, ṣe arokan ni mu asun-idakẹ wa. Nigbati mo ro gbogbo wahala mi ti mo ti ṣe s'ẹhin l'ori Sariyu arẹ si mu ọkan mi. Nigbana ni mo ranti ọrọ Oniwasu ti o sọ ninu Bibeli pe "Asan ninu asan, gbogbo rẹ asan ni."

OLOTU:—Ṣe itan iwọ ati Sariyu na l'o fẹ ma a ba lọ, tabi o ni itan titun miran lati sọ?

ALAPARA:—Ti emi ati ti Sariyu na ni, nitoripe ti nko ba pari rẹ nṣe ni yio wa l'ẹmi mi t'ọsan t'oru.

OLOTU:—O di ẹkelo ti itan rẹ na njade ninu Iwe "Irohin Yoruba?

ALAPARA:—Ẹkarun niyi.

OLOTU:—Njẹ o le sọ fun mi ninu Iwe Irohin ti awọn ojọwo ni o ti jade?

ALAPARA:—Idanwo ni ẹ fẹ fun mi ṣe ni tabi ohun ti mo ba wa ni e fẹ ki nsọ fun nyin?

OLOTU:—Ọrọ idano ko ni mo ba o sọ yi, ohun ti mo fẹ ki o mọ nipa ohun ti mo bere ni pe ki iwọ paapa le mọ bi o ti gba wa l'akoko si ati ki o le mọ bi o ti lo iwe wa si?

ALAPARA:—Ti o ba jẹ ti iyẹn ni mo le so ọ l'oju orun.

OLOTU:—O dara, sọ fun mi o?

ALAPARA:—Ekini jade ninu Iwe "Irohin Yoruba" ti ọjọ kọkanla oṣu kọkanla odun ti o kọja. Ẹkeji ni ti ọjọ kejidilogun oṣu kọkanla odun ti o kọja. Ẹkẹta ni ti ọjọ kẹsan oṣu kejila ti ọdun ti o kọja. Ẹkẹrin ni ti ọjọ kẹtalelogun oṣu kejila ọdun ti o kọja.

OLOTU:—O ṣeun, o ku aigbagbe ọjọ. Ma wa a ba irohin na lọ lati ibiti o gbe ti sọ de?

ALAPARA:—Ibiti mo gbe so de ni ibiti o ti gbe lo ba iyawo ọlọpa ja ni Otẹli, ti ọgọrun ponun ti mo fun un ni ẹkeji fi tun wọ igbo-rami-rami, ti ọran fi di ẹjọ kotu.

OLOTU:—Kini o tun sele l'ẹhinna? Ati bawo ni ẹ si ti pari ẹjọ na si?

ALAPARA:—Olotu, ẹ ṣe, ẹ ku suru. Ki ẹjọ na ki o to pari o na mi to igba ponun (£200). Lẹhin ti a pari ẹjọ na tan, mo wa bi i lere pe, kini ṣe ti a ko fi gburo awọn obi rẹ na? O ni "adugbo ti a wa yi jin si ti won pupọ ati pe nwon ko si kuku gburo pe mo ti de si ilu yi. Iyẹn ko jẹ ki nwọn le ni ifura pe mo nṣe ẹjọ kan."

Mo ni, o to gẹ ẹ, jẹki a pada si Eko, bi a ko ba mọ ibiti a nlọ a ni lati mọ ibiti a ti mbọ, ọna iwaju l'opin l'ẹhin ko pin. Nko i ti wi tan ti o fi tutọ s'oke ti o fi oju gba a. O ni kini nla! ki nde ilu mi ki ngma fi oju kan awọn ọbi mi, iyẹn ko ṣe-eṣe, wa a wa wọrọkọ fi ṣe ada ni, b'o ṣe adọta ponun ni ki o ba mi wa.

Mo ni, iṣe wo ni o ri l'ọwọ mi lati ọjọ ti a ti de ibi? O ni, "Iyẹn ki i ma a ṣe ẹjọ ti on o, o ko ni akaṣu ni o pata s'ẹfọ?" Ṣe ki a wa tun lọ s'Eko ki a pada ni tabi ewo ni ero rẹ? Nigbayi ni emi paapa wa to gbana jẹ ti mo bẹrẹsi palẹ ẹru mi mọ lati pada s'Eko. Nigbati Sariyu ri ipalẹmo yi nṣe ni o salọ s'ita, mo pe e pe e pe e ko da mi l'ohun, bẹni o ṣe sa lọ mọ mi lọwọ bamubamu.

Airi i ba sọro mọ yi ko arẹ ipalẹmo na ba mi, ni mo ba mu surupe ki nri ki nto lọ, oṣu kẹta ni mo to gburo rẹ pe o wa l'ọdọ okunrin kan. Ni mo ba yọ lọ si ibẹ lati ja iro ẹniti o so fun mi pe o wa ni ibe. Gbara ti o ti ri mi ni okere ni o ti ko ayesi—makaru ati awuruju balẹ, ti o nki mi wipe, Kọsini, ẹ ma wolẹ, nigbawo ni ẹ ti Eko de?

Mo kan nwo sua ni idahun ti fo mi ru, nitori okunrin ti mo ba pẹlu rẹ nṣe ayẹsi mi bi a ti ṣe fun ẹgbọn iyawo ẹni." Nwọn fun mi l'onjẹ nko le jẹ ẹ, nwọn fun mi ni ọti nko le mu u, iri oju mi bi ko si ti Ijọba ni bi ki nyọ ọbẹ ki mbẹ t'on t'ọkunrin na lori ni, ṣugbọn mo mu suru, mo ngbọ ọrọ t'on t'okunrin na bi t'ọko t'aya.

Nigbati mo woye ohun ti mo le ṣe ti ibinu mi ko fi ni han s'ode ni mo ba bi i lere wipe, aburo mi, kini ṣe ti ko fi ri iwe rẹ lati igbati o ti kuro ni ile? O ni, abi iwe mi ko ji'ṣe fun nyin? O ni mo ro pe emi pẹlu baale mi yio wa ki nyin ni irọlẹ ọtunla. Mo ni, nko ni si ni ile ni irọlẹ ọtunla, mo ni asiko ti ngo ba wa nile ma a jẹki ẹ gbọ, ni mo ba fi kuro ni ibẹ. Olotu mo dupẹ, ma mọ sọ iyoku ni ọsẹ ti mbọ l'agbara Ọlọrun.






## Ọmọ Jaguda mu Alhaji bu-sẹkun lojiji

KANO.

LENULOLOYI ni Alhaji Mohammadu Younis [illegible] Arab kan ti o wa [illegible] ni [illegible] bata meji (a pair of [illegible]


## ṢỌRA FUN OTUTU IBA










DỌKITA SỌ WIPE




Da OTUTU IBA rẹ duro gbe koro "ASPRO" meji mi
ARA RẸ YIO SI TUN YA-GAGA




# ỌBA AKRAN BẸ ILE IṢẸ EPO WO



Eyi ni aworan igbati Oloye Ọba C. D. Akran, Minista Alamojuto eto idagbasoke ipinlẹ Iwọ-Orun lọ ṣe ibẹwo ibiti awọn Oyinbo Oniṣowo "Epo Mobil Oil" gbe fi ẹrọ ifa 'po wọn si ni Afomo leti Agbadarigi. Oba ni o wo aebada ti mba awọn ọga ibi iṣẹ na sọrọ



Ọgbẹni W.M. Higgins, onimọ-iṣura-ilẹ ni o duro ti Ọba Akran ti o nṣe alaye fun Ọba na bi nwọn ti nṣe irinṣẹ iwalẹ





...woran oke yi ni ti Ọgbẹni Joseph Alder ọkan ninu awọn ọjọgbọ onisẹ-ogbin mẹfa ti mba Alamojuto iṣẹ ọgbin ati iṣura ilẹ Ipinlẹ Iwọ-Orun ṣiṣẹ. O nṣe alaye fun agbẹ kan nihin bi nwọn ti ṣe ntọju awọn adiẹ ninu ago-onibatiri

## Adajọ da ẹjọ iku fun ẹniti o pa iyawo re

ONLU.

NI ọjọ Aje ti [illegible] Ọgbẹni [illegible] Adajọ Kotu [illegible] Ipinlẹ Ila-Orun da ẹjọ iku fun ọdaran kan, Edwin Onyekwere, [illegible] ti o fi ada pa iyawo rẹ, Rosa Edwin, [illegible] A. Enoh [illegible] Okonkwo [illegible] kọja yi.

## Ẹniti o ji agogo gbe wẹwọn oṣu mẹrin

KANO.

LENULOLOYI ni Ọgbẹni T. T. Williams, Adajọ Kotu Kekere Kano [illegible] Ọgbẹni A. O. Roberts [illegible] Barclays Bank [illegible] (£10), [illegible] oṣu kejila ọdun ti o kọja yi.





AMAMA ni nwọn fi nkun onjẹ ọmọ yi o si ni alafia ati ilera ni igba gbogbo




AMAMA nfun ni ni agbara

fi AMAMA kun onjẹ nigba gbogbo

Manufactured by Glaxo Laboratories (Nigeria) Ltd., Apapa, Lagos.

Trade enquiries: R. B. Harding & Co. Ltd., Lagos, Aba and Kano. Sub-distributors in Ibadan: Bamford City Chemists.

# "Ihinrere si awọn Iransẹ Ọlọrun" (3)

*Lati ọwọ Evangelist J. J. Akande I, Ogbomọshọ*

ALAYE kẹta ti a o ṣe fun ẹnyin Iranṣẹ Ọlọrun loni ni nipa Ẹbun Isọtẹlẹ, ẹbun na jẹ ẹbun pataki ti Ọlọrun npin fun enia, yalna nipa Iran (Vision), Iṣe Apost. 9: 10-12, 16: 9-10 Awọn Ọba Kini, ori 22, ẹsẹ 7 ati ẹsẹ 16-37. Nipa Igbohun—Mat. 17: 5, Iṣe Awọn Aposteli 9: 4. Nipa Imọ-Ẹmi—Iṣe Awọn Aposteli 10: 19, tabi Nipa Ala—(Dream)—Gen. 37: 5-10 Gen. 42: 6-9; Numeri 12: 6. Orisi ọna mẹrin wọnyi ni Ọlọrun ngba fun enia ni ẹbun Isọtẹlẹ, Isọtẹlẹ si jẹ pataki to bẹẹ ti ọrọ Ọlọrun fi nkilọ fun wa ninu Tessalonika Kini, ori 5, ẹsẹ 20, bayi pe, "Ẹ maṣe kẹgan isọtẹlẹ."

Ki iṣe gbogbo awọn Iranṣẹ Ọlọrun lo ni ẹbun Isọtẹlẹ, afi ẹniti Ọlọrun ba fi fun. Ẹlomiran ti jijakadi gidigidi lati le ni ẹbun na, ṣugbọn a ko fifun un, nitoripe ẹbun ti o ba wu Ọlọrun lo npin fun olukuluku, nitorina ni a ṣe nkilọ fun wa ninu Kọrinti Kini ori 7, ẹsẹ 17, bayi pe, "ṣugbọn gẹgẹbi Ọlọrun ti pin fun olukuluku enia, bi Oluwa ti pe olukuluku, bẹni ki o si ma a rin."

Ọlọrun fun wa ni ẹbun Isọtẹlẹ awa onigbagbọ fi lẹ ma a mọ ohun ti o ba ṣokunkun loju wa. Bi a ba fẹ dawọle iṣẹ tabi owo pataki kan, Iran ni a le fi wadi bi iṣẹ tabi owo na yio ti yọri si, ti a o mọ ohun ti o yẹ ki a ṣe.

Awọn ẹlomiran wa ti nwọn ma a nkẹgan Isọtẹlẹ, iru awọn enia bẹ ẹ ti ki i gba Iran gbọ ti gbagbe ọrọ ti Ọlọrun sọ ninu Joel 2: 28, bayi pe, "Yio si ṣe, nikẹhin, Emi o tu ẹmi mi jade si ara enia gbogbo, ati awọn ọmọ nyin ọkunrin, ati awọn ọmọ nyin obinrin yio ma a sọtẹlẹ, awọn arugbo nyin yio ma a la ala, awọn ọdọmọkunrin nyin yio ma a riran."

Ileri ẹbun Isọtẹlẹ na ni a tun mu ṣẹ fun awọn ọmọ-ẹhin Jesu ninu Iṣe Awọn Aposteli ori2, lati ẹsẹ 1 titi de ẹsẹ 4, ni ọjọ Pentikosti ti Ẹmi Mimọ ba le wọn, ti nwọn si nfi ede titun sọrọ." Mo fẹ ki o ye nyin pe, gbogbo awa onigbagbọ isisiyi na ni anfani na wa fun, gẹgẹ bi a ti ṣe ri ẹri ọrọ na ka 'nu Iṣe Awọn Aopsteli 2: 38-39, bayi pe, "Ẹnyin o si gba ẹbun Ẹmi Mimọ, nitori fun nyin ni ileri na, ati fun awọn ọmo nyin, ati fun gbogbo awọn ti o jinna rere, ani gbogbo awọn ti Oluwa Ọlọrun wa yio pe."

Ko yẹ fun Onigbagbọ rara lati lọ ma a ṣe ayẹwo lọdọ babalawo tabi lọdọ alufa Imale atẹyanrin, awọn alaigbagbọ ati alainitiju lo nṣe bẹ ẹ. Dipo ti ẹ o fi ma a lọ ṣe ayẹwo lọdọ awọn alaigbagbọ wọnni, ẹnyin ọmọ igbala ni gbogbo Ijọ, ẹ kuku lọ sọdọ awọn Iranṣẹ Ọlọrun ti o ba ni ẹbun Isọtẹlẹ, ki ẹ si fi ọna ibere nyin siwaju Oluwa, Oluwa yio si tọ nyin si ọna rere.

Ẹnyin Iranṣẹ Ọlọrun ti a fun ni ẹbun Isọtẹlẹ, ẹ toju ẹbun na dada nipa adura, awẹ ati isora, ẹ maṣe jẹki eṣu sọ nyin di "wole-eke" nipa asọtẹlẹ-eke. Ẹ maṣe lo ẹbun na fun ifẹ owo, tabi fun panṣaga, ati ifẹkufẹ ara nyin. Ẹ maṣe sọ ohun ti Ọlọrun ko ba fihan nyin, bẹni ki ẹ maṣe alaisọ ohun ti Ọlọrun ba ran nyin lati sọ, ẹ maṣe gbagbe ọrọ nla ti Ọlọrun sọ ninu Deut. 18: 20, bayi pe, "ṣugbọn woli na ti o ba kugbu sọ ọrọ kan li orukọ Mi, ti Emi ko fun un li aṣẹ lati sọ, tabi ti o sọrọ li orukọ ọlọrun miran, ani woli na yio ku." Nitorina ẹ jẹki a kiyesara, ki Oluwa gba wa lọwọ ẹmi ẹtan gbogbo. Amin.

Bakanna ni ọrọ Ọlọrun nkilọ fun gbogbo Iranṣẹ Ọlọrun ninu Duet. 4: 2, bayi pe, "Ẹ ko gbọdọ bukun ọrọ na ti Mo palaṣẹ fun nyin, bẹni ẹnyin ko gbọdọ bu kuro ninu rẹ." Nitorina gbogbo ẹnyin ti Ọlọrun fun ni ẹbun Isọtẹlẹ, ẹ maṣe gbagbe ikilọ wọnyi, ki ẹ si ma lo ẹbun na lọna ti inu Ọlọrun yio fi ma a dun si nyin, ti awọn enia paapa yio si ma a tipasẹ nyin yin Ọlọrun logo.


Arẹ nṣe ọ bi?

Akurẹtẹ mba ọ ja na?

njẹ . . .



ta ẹdọki rẹ ji pẹlu

ANDREWS LIVER SALT




Bẹni, o ti ni agbara ju ẹnikẹni lọ—nigbati o ba ta ẹdọki rẹ ji, ile agbara inu ara rẹ! iyọ "Andrews Liver Salt" wa ni imurasilẹ pẹlu agbara itaji. O nṣiṣẹ ninu isanẹjẹ lati fun ẹdọki lagbara. O nwọ inu ara lọ si isalẹ lati ran ara lọwọ ki o le fọ ara rẹ mọ jade. Koko mu Andrews larọ lojojumọ, o ko si ni pẹ mọ ohun ti ifọnu yi yio se fun ọ. Awọ-ara rẹ yio ma a dan-gbere fun ilera, ara rẹ yio si ji-pepe fun agbara. Buroda, ọfẹrẹgẹgẹ—alagbara ni ọ fun iṣẹ. Gbogbo ara rẹ si kun fun kiki agbara ki o ba le jaiye lẹkun.

RA IYỌ

ANDREWS

LIVER SALT LONI!




NISISIYI . . . O wa fun tita ni oṣuwọn mimu lẹkanṣoṣo ati ninu awọn agolo ọlọmọde fun aṣunna owo.




Make a friend!

offer

GALLEON

NIGERIA'S FRIENDLY CIGARETTE

tastes expensive

... costs so little

Penny a stick!




1/8 for 20

# IROHIN LATI ILU OYINBO

# Apapọ Ẹgbẹ awọn Jagunjagun ti o ti jagun ri yika gbogbo agbaiye

PARIS.

NI ọjọ Aje ti ise ọjọ kẹdọgbọn osu yi ni Ọgbẹni Curtis Campaigne, Akowe-Agba Apapọ Ẹgbẹ Awọn Jagun-jagun ti o ti jagun ri yika gbogbo agbaiye (World Veterans Federation) ati Oludasilẹ Ẹgbẹ na se ikede pe awọn ti yan Dọkita John A. Sly gegebi Asoju ẹgbẹ na kini fun gbogbo Ipinlẹ ti o wa ni Iwọ-Orun Ilẹ-enia-dudu.

Ni ọjọ Aje na gan an ni Dokita Sly kuro ni ilu Paris lọ si ibudo isẹ rẹ ni Accra. Nigbati o mbọwa si ibi aye isẹ rẹ na ni Accra, o ya lọju ọna lọ si ilu Tangiers lati ba wọn se ipade keji ẹgbẹ na fun Eto Isẹ Owo gbogbo agbaiye ni Ilẹ-enia-dudu.

Yiyan ti nwọn ya Dọkita Sly gegebi Asoju Ẹgbẹ na jẹ isisẹ kini fun eto iranlọwọ lati ran awọn jagunjagun ti o ti jagun ri ni Ghana, Naijiria, Saro (Sierra Leone), Guinea ati Liberia lọwọ lati idasilẹ isẹ fun anfani awọn ti o ti jagun ri ati fun anfani gbogbo awọn enia ti o wa ni ibiti wọn ngbe.

Eyi jẹ itankalẹ si Ilẹ-enia dudu iranlọwọ ti Apapọ Ẹgbẹ Awọn Jagunjagun ti o ti jagun-ri ti fi ran awọn Eka Ẹgbẹ na ti o wa ni Ilẹ Asia lọwọ fun ọpọlọpọ ọdun sẹhin, ki awọn jagunjagun ti o ti jagun ri le ni ilọsiwaju ninu isẹ Isẹ-ọwọ ati Isẹ-agbẹ, nipa bayi, nwọn yio le se alekun onjẹ ojọ wọn ati ti awọn ẹlẹgbẹ wọn pẹlu. Ni igba pupọ ni Apapọ Ẹgbẹ Awọn ti o ti jagunri yika gbogbo agbaiye ma a nse iranlọwọ yi pẹlu ifọwọsowọpọ pẹlu Apapọ Ẹgbẹ Gbogbo Orilẹede Agbaiye (United Nations) ati awọn asayan Asoju wọn.

Ni ilu Los Angeles, California ni nwọn ti bi Dọkita Sly ni ọdun kẹtalelọgbọn sẹhin. O pari ẹkọ rẹ ni Ile Ekọ-giga Grinnel (Grinnell College) ni ilu Grinnel, Iowa ninu ọdun 1951. O si ti ipa bẹ e sisẹ fun ọdun mẹrin gegebi alakoso eto ẹkọ labẹ awọn Ẹgbẹ Liberia Mining Co., Ltd." ni adugbo kan ti o njẹ Bomi Hills ni Liberia.

(Wo oju ewe ketala)



Eyi ni aworan Dọkita John A. Sly, Asoju Apapọ Ẹgbẹ awọn jagun-jagun ti o ti jagunri yika gbogbo agbaiye fun gbogbo Ipinlẹ ti o wa ni Iwọ Orun Ilẹ-Enia-Dudu




# IROHIN LATI OKE-OKUN ATI OKE-ỌYA

## Adajọ sọ awọn onijibiti sẹwọn ọdun mẹsan

ABA.

LẸNULỌLỌYI ni Adajọ Agba Kotu Kekere kan sọ awọn ọdaran meji kan, Ayọ Adewale ati Sunday Okpara sẹwọn odun mẹsan o sọ ọdaran kini sẹwọn ọdun marun o si sọ ọdaran keji sẹwọn ọdun mẹrin; nitoripe nwọn jẹbi ẹjọ ole ati alọnilọwọgba ti awọn ọlọpa ba wọn ṣe pe, nwọn lọ lu onisowo Aba kan ni jibiti, nwọn si ji i ni agogo ọrun-ọwọ meji.

Ẹjọ ti awọn ọlọpa ro fun Adajọ ni pe awọn ọdaran mejeji na dibọn, nwọn duna-dura bi ẹnipe nwọn nfẹ lati ra awọn agogo na ni nwọn ba fi ji wọn lọ. Awọn ọdaran na ni awọn ko jẹbi: nitoripe awọn ko ni ero lati ji awọn agogo na, awọn jade lati lọ mu owo ti awọn yio fi ra wọn ni, ni Adajọ ba fi sọ wọn sẹwọn.

## Baba ati awọn ọmọ rẹ meji iona

FUNTUA.

NI alẹ ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kọkandinlogun oṣu yi ni ina kan jo baba kan ati awọn ọmọ rẹ meji pa nigbati ile-ahere ti nwọn nsun ninu rẹ gbina. Iya awọn ọmọ na ti o wa pẹlu wọn ninu ile-ahere na ko ku sinu ijamba ina na ṣugbọn ina na jo o pupọ. Awọn ọlọpa koi ti mọ ohun ti o fa ina na ti o ṣẹlẹ.

## *Awọn ọmọ ẹgbẹ NEPU fẹ ṣa kọtu Ijọba Ibilẹ Jos ti*

JOS.

AWỌN ọmọ Ẹgbẹ NEPU ti ẹka Jos ti fohunṣọkan sọ pe awọn ko ni igbẹkẹle si Malam Muhammadu, Alkali Agba Kotu Ijọba Ibilẹ Jos, nwọn si ti halẹ kọwe ẹbẹ kan si Ajẹlẹ Agba ti Agbegbe Plateaus pe, awọn yio ṣa Kotu Alkali na ti lati ọjọ Eti ti iṣe ọjọ kẹdogun oṣu yi.

## Adajọ sọ awọn fọle fọle s'ẹwọn ọdun mẹta mẹta

CALABAR.

NI ọjọ Ọjọbọ ti iṣe ọjọ kẹrinla oṣu yi ni Adajọ Agba Kotu Kekere Calabar sọ awọn ọdaran mẹta kan, Kalu Agwu, ẹni ọdun mẹtadilogoji, Uche Onwukaja, ẹni ọdun mẹrinlelogun ati Echem Onuka, ẹni ogun ọdun, s'ẹwọn odun mẹta mẹta nitoripe nwọn jẹbi ẹsun ti awọn ọlọpa mu wọn fun pe nwọn f'ole okunrin kan, Ogbeni Felix Obiogha, nwọn si tun ko ẹru ọlọgbọn ponun ati ṣile mẹdogun abọ nibẹ. Awọn ọdaran na ni idajo adajo yi ko tẹ awọn l'ọrun awọn yio si gbe ẹjọ na lọ siwaju ni Kotu-kotẹmi-lọrun.

## *Adajọ sọ ẹniti o ngmu ọbẹ dani kiri ilu sẹwọn oṣu mẹsan*

ENUGU.

NI ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kẹrindinlogun oṣu yi ni Adajọ Kotu Kekere Enugu sọ ọdaran kan Okere Ndukwe sewọn oṣu mesan nitoriti o jẹbi ẹjọ ti awọn ọlọpa ba a ṣe pe o ngmu ọbẹ olojumeji (dagger) dani kakiri.

Ọdaran na sọ fun Adajọ pe on jẹbi ẹsun na ti awọn ọlọpa ka si on lọrun, ṣugbọn lati igbati awọn ole ti ji on ni owo ni on ti nfi ọbẹ olojumeji na da-aabo bo ara on.



Aworan yi ni ti Pidanpidan ti o fẹ rẹ ara rẹ l'ahọn nigbati nwọn nṣe ẹyẹ fun Macmillan ni Afin Ọba Zaria



Aworan yi ni ti ẹniti o fi ara rẹ ṣe ẹṣin ti nwọn si gun un fun ẹyẹ Macmillan ni Afin Ọba Zaria



